**ÌKÉDE ÀṢÀ ÌṢỌ́ ÀṢÍRÍ**
**(NOTICE OF PRIVACY PRACTICES)**

Ọjọ́ Ìṣiṣẹ́: Oṣù Kẹrin Ọjọ́ 14, Ọdún 2003
Àtúnṣe: Oṣù Kẹta Ọjọ́ 5, Ọdún 2026

Ìkéde yìí ṣàpèjúwe bí àlàyé ìṣègùn nípa rẹ ṣe lè ní ìlò àti ṣíṣé àfihàn, àti bí o ṣe lè gba ànfààní láti wọlé sí àlàyé yìí. JỌ WỌ́ ṢÀYẸ̀WÒ RẸ̀ DÁRADÁRA.

Fún àwọn àkọsílẹ̀ Ìṣòro Lílo Ohun Áìsedédé (SUD) Apá Kejì (2), ìkéde yìí ṣàpèjúwe:

- Bí àlàyé ìlera apá kejì (2) nípa rẹ ṣe lè ní ìlò àti ṣíṣé àfihàn
- Àwọn ẹ̀tọ́ rẹ tó jẹmọ́ àlàyé ìlera rẹ
- Bí o ṣe lè fi ẹ̀sùn kàn nípa ìrúfin àṣírí tàbí ààbò àlàyé ìlera rẹ, tàbí nípa àwọn ẹ̀tọ́ rẹ tó jẹmọ́ àlàyé rẹ

O ní ẹ̀tọ́ láti gba ẹ̀dà ìkéde yìí (ní bi ìwé tàbí lori ẹ̀rọ ìgbàlódé) ààti láti jíròrò rẹ̀ pẹ̀lú ọ̀gá àṣírí wa ní 833-718-1043 tàbí privacyofficer@trinity-health.org tí o bá ní àwọn ìbéèrè míràn.

A mọ̀ pé àlàyé nípa ìlera rẹ jẹ́ ohun tí ó kan ọ lára gidigidi, àti pé a ti pinnu láti dáàbò bo àṣírí rẹ. Jọwọ́ kà Ìkéde Àṣà Ìṣọ́ Àṣírí yìí yékéyéké. Ó ṣàpèjúwe bí a ṣe lò àti ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò **(PHI)** rẹ.

Òfin Gbígbé àti Ìṣòótọ́ Ìmọ́ Ìlera ti Ọdún 1996, àti Òfin Ìmọ̀ Ẹ̀rọ Àlàyé Ìlera fún Ètò Ọrọ̀ Ajé àti Ìlera Ìṣègùn (tí a rí nínú Àkọlé Kẹtàlá ti Òfin Ìmúpadàbọ̀sípò àti Ìdókòwò Amẹ́ríkà ti Ọdún 2009) (tí a ń pè papọ̀ ní "HIPAA"), gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àtúnṣe rẹ̀ láti ìgbà dé ìgbà, béèrè pé kí a ṣọ́ àṣírí àlàyé ìlera aláìsàn tí a lè dámọ̀ fún ẹni kọ̀ọ̀kan **(àlàyé yìí jẹ́ "àlàyé ìlera tí ó ni ìdáàbòbò" àti pé a ń tọ́ka sí rẹ̀ níbí gẹ́gẹ́ bí "PHI").**

A tún nílò láti pèsè Ìkéde Àṣà Ìṣọ́ Àṣírí nípa Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) fún àwọn aláìsàn. A óò lò tàbí ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ nìkan gẹ́gẹ́ bí òfin ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀ tó ti gbà láàyè tàbí béèrè. Ìkéde yìí ní se pẹ̀lú Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ tí ó wà lábẹ́ ìṣàkóso wa pẹ̀lú àwọn àkọsílẹ̀ ìṣègùn tí a ṣẹ̀dá.

Ìkéde yìí ní se pẹ̀lú ìpèsè ìtọ́jú ìlera nípaṣẹ̀ ilé ìwòsàn wa àti àwọn òṣìṣẹ́ ìṣègùn rẹ̀ nínú ilé ìwòsàn àkọ́kọ́, gbogbo àwọn ẹ̀ka ìtọ́jú ìta, àwọn ètò ìtọ́jú Ìṣòro Lílo Ohun Áìsedédé (SUD) Apá Kejì (2) àti àwọn ilé-ìwòsàn kékeré. Ìkéde yìí tún ní se pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ àyẹ̀wò ìlò àti ìwòye ìdára ti Trinity Health àti ilé ìwòsàn wa gẹ́gẹ́ bí ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health, ètò ìtọ́jú ìlera Kátólíìkì tí ó ní àwọn ohun àmójútó tí ó wà ní àwọn ìpínlẹ̀ pọ̀ jákèjádò Orílẹ̀-Èdè Amẹ́ríkà.

## I. Ìlò tàbí Àfihàn Tí A Gbà Láàyè

**A. Ìtọ́jú:** A óò lò àti ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ láti pèsè, darí, tàbí ṣàkóso ìtọ́jú ìlera rẹ àti àwọn iṣẹ́ tó jẹmọ́ láti mú àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ṣẹ. Àwọn wọ̀nyí ni àwọn àpẹẹrẹ bí a ṣe óò lò àti/tàbí ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ:

i. Sí dókítà tó ń tọ́jú rẹ, àwọn dókítà tó ń fún ní ìmọ̀ràn, àti àwọn olúpèsè ìtọ́jú ìlera míràn tí wọ́n ní ẹ̀tọ́ sí fún àlàyé bẹ́ẹ̀ nínú ìtọ́jú àti àbótó rẹ.

ii. Láti darí ìtọ́jú rẹ (fún àpẹẹrẹ, sísètò àpẹjọ) pẹ̀lú wa àti àwọn olúpèsè ìtọ́jú ìlera míràn bíi orúkọ, àdírẹ́ẹ̀sì, ibi iṣẹ́, ilé-iṣẹ́ ìmọ́ ìlera, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

iii. Láti kan sí ọ gẹ́gẹ́ bí ìrán ni été pé o ní àpẹjọ fún ìtọ́jú tàbí ìtọ́jú ìṣègùn ní àwọn ohun àmójútó wa.

iv. Láti pèsè àlàyé fún ọ nípa àwọn àṣàyàn ìtọ́jú míràn tàbí àwọn àǹfààní tàbí iṣẹ́ míràn tó jẹmọ́ ìlera.

v. Tí o bá jẹ́ ẹlẹ́wọ̀n nínú ilé ìtọ́jú àtúnṣe tàbí tí o wà lábẹ́ ìmójútó òṣìṣẹ́ ìjọba tí ń ṣọ́ òfin, a óò ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ sí ilé ìtọ́jú àtúnṣe tàbí òṣìṣẹ́ ìjọba tí ń ṣọ́ òfin gẹ́gẹ́ bí òfin ti béèrè.

**B. Ìtọ́jú Ìṣòro Lílo Ohun ségesège (SUD):** A pèsè àwọn ètò ìtọ́jú ìṣòro lílo ohun ségesège tí àwọn òfin 42 CFR Apá Kejì (2) ń bójú tó (tí a ń pè ní Ètò "Apá Kejì 2"). Tí o bá gba irú ìtọ́jú yìí, a lè béèrè lọ́wọ́ rẹ láti fọwọ́ sí fọ́ọ̀mù àṣẹ gbogbogbò fún ìtọ́jú Ètò Apá Kejì (2). Àṣẹ ìkọ̀wé fún àwọn ìtọ́jú, sì sanwó àti iṣẹ́ lè jẹ gbígba ẹẹkan àti pé ó lè ṣe àtìléyìn fún àwọn ìlò ọjọ́ iwájú ti Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún àwọn ète ìtọ́jú, sìsanwó àti iṣẹ́ láìsí àṣẹ àfikún lábẹ́ HIPAA.

i. Tí a bá gba tàbí ṣọ́ àlàyé èkejì nípa rẹ láti sètò ìtọ́jú ìṣòro lílo ohun ségesège tí àwọn òfin 42 CFR Apá Kejì (2) ń bójú tó (Ètò "Apá Kejì 2") nípasẹ̀ àṣẹ ìkọ̀wé kan tí o pèsè sí Ètò Apá Kejì (2) láti lò àti ṣé àfihàn àkọsílẹ̀ Ètò Apá Kejì (2) fún àwọn ìdí ìtọ́jú, sìsanwó tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera, a lè tún lò àti ṣé àfihàn àkọsílẹ̀ Ètò Apá Kejì (2) rẹ fún àwọn ìtọ́jú, sìsanwó àti àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàpèjúwe nínú Ìkéde yìí.

ii. Tí a bá gba tàbí bójutó àkọsílẹ̀ Ètò Apá Kejì (2) rẹ nípasẹ̀ àṣẹ pàtàkì tí o pèsè sí wa tàbí ẹlòmíràn, a óò lò àti ṣé àfihàn àkọsílẹ̀ Ètò Apá Kejì (2) rẹ nìkan gẹ́gẹ́ bí o ṣe gbà láàyè ní gbangba nínú àṣẹ rẹ gẹ́gẹ́ bí a ti pèsè sí wa.

iii. Kìyòsì ìṣẹ̀lẹ̀ kankan ti yio mu wa lò tàbí ṣé àfihàn àkọsílẹ̀ Ètò Apá Kejì (2) rẹ, tàbí ẹ̀rí tí ó ṣàpèjúwe àlàyé tí ó wà nínú àkọsílẹ̀ Ètò Apá Kejì (2) rẹ, nínú àwọn ìgbẹ́jọ́ aráàlú, ọ̀daràn, ìṣàkóso, tàbí ìgbìmọ̀ aṣòfin èkejì nípaṣẹ̀ àṣẹ Àpapọ̀, Ìpínlẹ̀, tàbí àdúgbò, lòdì sí ọ, àyàmfi tí àṣẹ rẹ tàbí àṣẹ ilé-ẹjọ́ bá gbà láàyè rẹ̀ lẹ́yìn tí ilé-ẹjọ́ bá jẹ́ kí o mọ̀ nípa àṣẹ ilé-ẹjọ́ náà.

iv. Ìkọ́wọ́jọ. O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè fún yíyọ ara rẹ jáde nínú àwọn ìgbòkègbodò Ìkọ́wọ́jọ. kan pàtó tó jẹmọ́ ìtọ́jú ààsedédé Lílo Oògùn.

v. Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ Nípa Àwọn Àkọsílẹ̀ Apá Kejì (2). Àfikún ẹ̀tọ́ aláìsàn tí a ṣàlàyé nínú Ìkìlọ̀ yìí kan sí gbogbo ètò ìṣègùn, títí kan àwọn àkọsílẹ̀ Apá Kejì (2).

**C. Ìsanwó:** A óò lò àti ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) nípa rẹ fún àwọn ète ìsanwó. Àwọn wọ̀nyí jẹ́ àpẹẹrẹ bí a ṣe máa ń lò àti/tàbí ṣé àfihàn ìsọfúnni ìlera ara ẹni rẹ (PHI):

i. Sí ilé-iṣẹ́ adójútìfò, olùsanw méràn, alàkóso méràn, ètò ìlera tàbí olùpèsè ìtọ́jú ìlera mìíràn (tàbí àwọn aṣojú tí wọ́n ti fún ni àṣẹ dáadáa) fún àwọn ète sísanwó gẹ́gẹ́ bí ìpinnu ohun to kápá, ẹ̀tọ́ ríni, ìfọwọ́sí/àṣẹ ṣáájú fún ìtọ́jú, ìgbéwọlé sìsanwó, ìṣàkóso àwọn ẹ̀tọ́, àyẹ̀wò sìsanwó padà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

ii. Sí àwọn àjọ tin gba owó àti àwọn ẹgbẹ́ míràn tí wọ́n kópa nínú gbígba ìsanwó fún ìtọ́jú.

**D. Àwọn òsìṣẹ́ Ìtọ́jú Ìlera:** A óò lò àti ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún àwọn ète àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera. Àwọn wọ̀nyí jẹ́ àwọn àpẹẹrẹ bí a ṣe óò lò àti/tàbí ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ:

i. Fún ìṣàkóso ọ̀ràn, ìdánimọ̀ ìdára, ìlò, ìṣirò, àyẹ̀wò ìwé, ìgbèrò ìtúsílẹ̀, àwọn iṣẹ́ ìlera àwùjọ tó jẹmọ́ ìmúdára ìlera tàbí ìdínkù ìdíyelé ìtọ́jú ìlera, ẹ̀kọ́, ìfọwọ́sí, fífún ni láṣẹ, àti àwọn iṣẹ́ ìfọwọ́pẹ̀lẹ́ àṣeyọrí.

ii. Sí àwọn olùmọ̀ràn, àwọn akọ̀ọ̀yé, àwọn olùṣàyẹ̀wò ìwé, àwọn agbẹjọ́rò, àwọn ilé-iṣẹ́ ìkọ̀wé, àwọn olúpèsè ìmọ̀ ẹ̀rọ àlàyé àti ìpamọ́ àwọsánmón, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**E. Àwọn Ìlò àti Àfihàn Míràn:** Gẹ́gẹ́ bí ara ìtọ́jú, sìsanwó, àti àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera. A lè tún lò Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún àwọn ète wọ̀nyí tó tẹ̀lé:

i. **Ìkówójọ àti Ìpolongo:** A óò lò àti lè tún ṣé àfihàn apá kan Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ, pẹ̀lú ìpilẹ̀ṣẹ̀ tó jẹmọ́, fún àwọn iṣẹ́ ìkówójọ àti ìpolongo kan pàtó. Fún àpẹẹrẹ, a lè lò tàbí ṣé àfihàn àlàyé ìpínlẹ̀ rẹ, àwọn ọjọ́ ìtọ́jú rẹ, àlàyé nípa dókítà tó ń tọ́jú rẹ, ẹ̀ka iṣẹ́ àti àlàyé àbájáde, àti pé a lè béèrè fún ẹ̀bùn owó lọ́wọ́ rẹ. Ìkówójọ ki Ìkówójọ àti ìpolongo tí a rán sí ọ yóò jẹ́ kí o mọ̀ bí o ṣe lè lo ẹ̀tọ́ rẹ láti <u>jáde</u> kúrò ninu gbígba àwọn àbájáde tó jọra ní ọjọ́ iwájú.

ii. **Ìwádìí Ìṣègùn:** A óò lò àti ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ ní ọ̀nà tí a gbà láàyè sí àwọn olùwádìí ìṣègùn tí wọ́n gba ìyònda rẹ̀ fún àwọn ìṣẹ́ ìwádìí ìṣègùn tí a fọwọ́ sí. Àwọn olùwádìí nílò láti dáàbò bo gbogbo Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) tí wọ́n gba.

iii. **Awọn Iṣẹ́ Ìgbéga Ìlera:** A óò lò àti ṣé àfihàn apá kan Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún àwọn iṣẹ́ ìgbéga ìlera kan pàtó. Fún àpẹẹrẹ, orúkọ rẹ àti àdírẹ́ẹ̀sì rẹ yóò jẹ ìlò láti rán ìwé ìròyìn gbogbogbò tàbí àlàyé kan pàtó sí ọ tí ó dá lórí àwọn ìlera rẹ tí ó kàn ó.

iv. **Òye Atọwọdá**: A ń lò ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣe àtìléyìn ìtọ́jú àti ìtọ́jú ìṣègùn tí ó lè lo Òye Atọwọdá (AI). Ìmọ̀ ẹ̀rọ Òye Atọwọdá ń lò àlàyé láti kọ́ àti mú iṣẹ́ Òye Atọwọdá (AI) dára sí i. Àwọn alábàákẹ́gbẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ ìjìnlẹ̀ wa, pẹ̀lú àwọn tí wọ́n ní ìmọ̀ ẹ̀rọ Òye Atọwọdá, gbọdọ̀ ṣọ́ àlàyé ní ìkọ̀kọ̀ lábẹ́ òfin tó yẹ.

v. **Àlàyé Tí A Ti Yọ dídánimọ̀ Kúrò**: A lè lò àti ṣé àfihàn àlàyé tí a ti yọ dìdánimọ̀ kúrò, tí ó túmọ̀ sí pé kò ní orúkọ rẹ, àdírẹ́ẹ̀sì rẹ, tàbí àwọn àlàyé ẹnikéni tí ó lè dámọ̀ tàarà, gẹ́gẹ́

bí òfin àpapọ̀ ti béèrè. Lẹ́yìn tí a bá ti yọ ìdánimọ̀ kúrò nínú àlàyé rẹ, a kò tún ka sí àlàyé ìlera tí ó ni ìdáàbòbò món lábẹ́ HIPAA àti pé kò wà lábẹ́ àwọn ìdáàbòbò àṣírí kannáà.

F. **Àwọn Òfin Tó Ń Kára Ju:** Àwọn òfin ìpínlẹ̀ níbi tí o ń gbé lè jẹ́ tí ó ń kára ju HIPAA lọ ní àwọn àgbègbè kan. A óò tẹ̀síwájú láti tẹ̀lé àwọn òfin ìpínlẹ̀ tó ń kára ju wọ̀nyí.

  i. **Àwọn Òfin Ìpínlẹ̀ Tó Ń Kára Ju:** Òfin ìpínlẹ̀ ń kára ju nígbàtí ẹni kọ̀ọ̀kan bá ní ẹ̀tọ́ sí àwọn àkọsílẹ̀ tó pọ̀ ju ohun tí HIPAA gbà láàyè lọ. Òfin ìpínlẹ̀ tún ń kára ju nígbàtí àwọn àkọsílẹ̀ bá gba ìdáàbòbò tó pọ̀ ju lọ kúrò nínú àfihàn nípaṣẹ̀ òfin ìpínlẹ̀ ju ohun tí HIPAA gbà láàyè lọ. Ní àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí a bá pèsè ìtọ́jú sí aláìsàn tí ó ń gbé ní ìpínlẹ̀ tó wà la gbègbè, a óò tẹ̀lé òfin ìpínlẹ̀ tó yẹ tí ó ń kára ju.

G. **Pàṣípààrọ̀ Àlàyé Ìlera:** A pín àwọn àkọsílẹ̀ ìlera rẹ ní ọ̀nà ayélujára tàbí ní ọ̀nà míràn pẹ̀lú àwọn Pàṣípààrọ̀ Àlàyé Ìlera ("HIEs") tí ó ń se pàṣípààrọ̀ àwọn àkọsílẹ̀ ìlera pẹ̀lú àwọn HIE míràn. A tún lò ìmọ̀ ẹ̀rọ pàṣípààrọ̀ àbájáde (bíi àwọn iṣẹ́ àtẹ̀jíṣẹ́ tààrà, olúpèsè iṣẹ́ àlàyé ìlera ("HISP"), àti àwọn ojú-òpó olúpèsè) pẹ̀lú Àkọsílẹ̀ ẹ̀rọ ìgbàlódé Ìlera rẹ ("EHR") láti pín àwọn àkọsílẹ̀ ìlera rẹ fún àwọn tí a le gbà láàyè pẹ̀lú ìtẹ̀síwájú ìtọ́jú àti ìtọ́jú ìṣègùn. Àwọn HIE àti ìmọ̀ ẹ̀rọ pàṣípààrọ̀ àbájáde ń jẹ́ kí pínpín àwọn àkọsílẹ̀ ìlera rẹ ṣeéṣe láti mú dìdára àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tí a pèsè dára sí i. Àwọn àkọsílẹ̀ ìlera tí a pín yóò pẹ̀lú, tí ó bá yẹ, àwọn àyẹ̀wò ìṣègùn tó ṣòro bíi HIV/AIDS, àwọn àrùn tí a ń tan nípasẹ̀ ìbálòpọ̀, àlàyé ẹ̀dá, ìlera ọpọlọ, àti ìṣòro lílo ọtí tàbí ohun to'n se ségesége. HIE àti àwọn olúpèsè ìmọ̀ ẹ̀rọ àbájáde pàṣípààrọ̀ ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí alábàákẹ́gbẹ́ òwò wa àti, nínú ṣíṣe iṣẹ́ ní orúkọ wa, wọ́n yóò gbé, ṣọ́ àti pamọ́ Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún ìtọ́jú, sìsanwó àti àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera àti àwọn míràn tí a gbà láàyè. Àwọn HIE àti àwọn olúpèsè àbájáde ìmọ̀ ẹ̀rọ pàṣípààrọ̀ ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí alábàákẹ́gbẹ́ òwò wa àti, nínú ṣíṣe iṣẹ́ ní orúkọ wa, wọ́n yóò gbé, ṣọ́ àti pamọ́ Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún ìtọ́jú, ìsanwó àti àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera àti àwọn ète míràn tí a gbà láàyè. Òfin tó yẹ lè pèsè ẹ̀tọ́ fún ọ láti dín, yan láti wọlé, tàbí yan láti jáde kúrò nínú HIE (s). Fún àlàyé síi, jọwọ́ kan sí Ọ̀gá Àṣírí wa ní 833-718-1043, tàbí o lè fi ìméèlì ránṣẹ́ sí wa ní privacyofficer@trinity-health.org.

## II. Gbígbà Láàyè lílò tàbí Àfihàn Tí o Pẹ̀lú Ànfààní Fún Ọ Láti Gbà tàbí Tako

A. **Ẹbí/Àwọn Ọ̀rẹ́:** A óò ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) nípa rẹ sí ọ̀rẹ́ tàbí ọmọ ẹbí tí ó kópa nínú tàbí tí ó ń san owó fún ìtọ́jú ìṣègùn rẹ. O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ má jẹ pínpín. Ní àfikún, a óò ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) nípa rẹ sí àjọ tí ó ń ràn wa lọ́wọ́ nínú àwọn iṣẹ́ ìdásí ajálù kí ẹbí rẹ bà lè jẹ́ kí wọn mọ̀ nípa ipò ìlera rẹ, ipò rẹ, àti ibi tí o wà.

B. **Àtòjọ Ilé Ìwòsàn:** A lè fi àlàyé kan pàtó nípa rẹ sínú àtòjọ nígbàtí o bá jẹ́ aláìsàn ilé ìwòsàn. Àlàyé yìí yóò ni se pẹ̀lú orúkọ rẹ, ibi tí o wà, ipò ìlera rẹ gbogbogbò (fún àpẹẹrẹ, dára díẹ̀, ìdúróṣinṣin, ewu, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ) àti ẹ̀sìn tí o jẹ́ ọmọ rẹ̀. Àlàyé àtòjọ, àyàfi ẹ̀sìn tí o jẹ́ ọmọ rẹ̀, yóò jẹ́ ṣíṣé àfihàn sí àwọn ènìyàn tí wọ́n béèrè fún ọ nípa orúkọ rẹ. O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí orúkọ rẹ má jẹ fífi sínú àtòjọ wa. Tí o bá béèrè láti jade kúrò nínú àtòjọ, a kò lè jẹ́ kí àwọn alábẹ̀wò mọ̀ nípa wíwà rẹ, ibi tí o wà, tàbí ipò ìlera rẹ gbogbogbò.

**C. Àlàyé Àtòjọ Ìtọ́jú Tẹ̀mí**: pẹ̀lú ẹ̀sìn tí o jẹ́ mọ ọ, a o fi fun ọmọ ẹgbẹ́ alùfáà, kódà tí wọ́n kò bá béèrè rẹ nípasẹ̀ orúkọ.  Olùtọ́jú Tẹ̀mí je ọmọ ẹgbẹ́ eleto ilera, ati pẹ̀lú a le kan si won nipa itoju re.  O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí won ma se fi orúkọ rẹ fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ alùfáà.

**D. Àwọn Oníròyìn:** A óò tú àlàyé àtòjọ ohun àmójútó sílẹ̀ fún àwọn oníròyìn (láìfi ẹ̀sìn tí o jẹ́ mọ ọ sínú rẹ̀) tí àwọn oníròyìn bá béèrè fún àlàyé nípa rẹ nípa lílo orúkọ rẹ.  Ṣàkíyèsí pé o lè kọ̀ láti jẹ́ fífi sínú àtòjọ.

## III. Ìlò tàbí Àfihàn Tí Ó Nílò Àṣẹ Rẹ

**A. Ìpolongo:** Lábẹ́ àwọn ìyàsọtọ̀ kan tí ó ní ìdíwọ́, àṣẹ ìkọ̀wé rẹ nílò ní àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí a bá gba owó sisan tàárà tàbí tí kìise tàárà ní pàṣípààrọ̀ fún ṣíṣe ìsọ̀rọ̀ sí ọ tí ó ń fún ọ níni ìmọ̀ràn láti ra ọjà tàbí iṣẹ́ tàbí fún àfihàn sí elomiran tí ó fẹ́ ṣe ìpolongo àwọn ọjà tàbí iṣẹ́ wọn sí ọ.

**B. Ìwádìí:** A óò gba àṣẹ ìkọ̀wé rẹ láti lò tàbí ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ àti/tàbí àwọn àpẹẹrẹ àsọ ara fún àwọn ète ìwádìí nígbàtí HIPAA tàbí àwọn òfin àti ìlànà ìwádìí ìṣègùn bá béèrè rẹ̀.

**C. Àwọn Àkọsílẹ̀ Ìtọ́jú Ọpọlọ:** nílò Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àti àfihàn àwọn àkọsílẹ̀ ìtọ́jú ọpọlọ, nílò àṣẹ akọlẹ rẹ.

**D. Àwọn Àkọsílẹ̀ Ìmọ̀ràn SUD Apá Kejì (2):** A gbọdọ̀ gba àṣẹ akọlẹ ọtọọtọ rẹ ṣáájú ṣíṣé àfihàn àwọn Àkọsílẹ̀ Ìmọ̀ràn SUD miran tí ó lè wà nínú àkọsílẹ̀ Apá Kejì (2) rẹ àyàfi tí Apá Kejì (2) bá gbà láàyè ní ọ̀nà míràn. Àṣẹ fún àfihàn Àwọn Àkọsílẹ̀ Ìmọ̀ràn SUD kò ní jẹ beeni kò ní jẹ dídapọ̀ mọ́ àṣẹ miran.

**E. Títà Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI):** Lábẹ́ àwọn àyàsọtọ̀ kan tí ó ní gbèdéke, àwọn àfihàn tí ó jẹ́ títà Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) nílò àṣẹ ìkọ̀wé rẹ.

**F. Àwọn Ìlò àti Àfihàn Míràn:** Àwọn ìlò tàbí àfihàn míràn ti Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) tí a kò ṣàpèjúwe nínú Ìkéde Àṣà Ìṣọ́ Àṣírí yìí lè béèrè fún àṣẹ ìkọ̀wé rẹ (tí HIPAA kò bá gbà láàyè rẹ̀). Àwọn àṣẹ ìkọ̀wé yóò jẹ́ kí o mọ̀ ìdí tí a fi ń lò Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ.  O ní ẹ̀tọ́ láti fagi lé àṣẹ kan nígbàkigbà.

## IV. Ìlò tàbí Àfihàn Tí Ó jẹmọ́ gbígbàlàyè tàbí Tí Òfin Béèrè Nípa Ìlànà Àwùjọ tàbí Òfin Láìsí Àṣẹ Rẹ

**A. Àwọn Ète Ìmúṣiṣẹ́ Òfin:** A lè ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún àwọn ète ìmúṣiṣẹ́ òfin gẹ́gẹ́ bí òfin ti gbà láàyè, bíi ìdámọ̀ afurasi ìwà ọ̀daràn tàbí ẹni tí ó sọnù tàbí pípèsè àlàyé nípa olùjìyà ìwà ọ̀daràn tàbí ìwà ọ̀daràn tó kan ọ.

**B. Bí Òfin Ṣe Béèrè:** A óò ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) nípa rẹ nígbàtí òfin àpapọ̀, ti ìpínlẹ̀, tàbí ti àdúgbò bá béèrè rẹ̀.  Àwọn àpẹẹrẹ pẹ̀lú àwọn àfihàn ní ìdáhùn sí àṣẹ ilé-ẹjọ́ / ìpè ilé-ẹjọ́, ìròyìn dandan ti ìpínlẹ̀ so pe (fún àpẹẹrẹ, àwọn ọgbẹ́ ìbọn, àwọn ti won fara kásá ìlòkulò ìtọ́jú ọmọ), àwọn ìwádìí ijọba, tàbí àlàyé tó ṣe pàtàkì láti tẹ̀lé àwọn òfin míràn bíi ìsanwó àwọn òṣìṣẹ́ tó farapa tàbí àwọn òfin tó jọra. A óò fisùn àyípadà òògùn àti àlàyé tó jẹmọ́ iṣẹ́ jìbìtì ìwé òògùn sí àwọn àjọ ìjọba tí ń ṣọ́ òfin àti àwọn àjọ ìlànà.

C. **Abójútó Ìlera Àwùjọ tàbí Ààbò:** A óò lò àti ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) láti yẹra fún ewu tó le koko sí ìlera àti ààbò ẹni kọ̀ọ̀kan tàbí àwùjọ. Àwọn àpẹẹrẹ pẹ̀lú àwọn àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) sí àwọn olùṣèwádìí ìpínlẹ̀ nípa ìtọ́jú tàbí sí àwọn àjọ ìlera àwùjọ nípa àwọn àjẹsára, àwọn àrùn tó ń tàn kálẹ̀, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A óò lò àti ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) fún àwọn iṣẹ́ tó jẹmọ́ ìdára, ààbò tàbí ipá Oúnjẹ àti Òògùn ń ṣàkóso, pẹ̀lú gbígba àti ìròyìn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí kò dára, ìtọ́pa, àti ìranlọ́wọ́ nínú àwọn ìpèpadà ọjà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

D. **Àwọn Olùṣèwádìí Ikú, Àwọn Onímọ̀ Ìṣègùn Tó Ń Ṣàyẹ̀wò Ikú, Àwọn Olùdarí Iṣẹ́ Ìsìnkú:** A óò ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ sí olùṣèwádìí ikú tàbí onímọ̀ ìṣègùn tó ń ṣàyẹ̀wò ikú. Fún àpẹẹrẹ, èyí yóò jẹ́ dandan láti le se ìdámọ̀ ẹni tí ó ti kú tàbí láti pinnu ìdí ikú. A lè tún ṣé àfihàn àlàyé ìṣègùn rẹ sí àwọn olùdarí iṣẹ́ ìsìnkú bí ó ṣe nílò láti mú àwọn iṣẹ́ wọn ṣẹ.

E. **Ìpèsè Ẹ̀yà Ara:** A óò ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) sí àjọ tàbí ẹgbẹ́ ìpèsè ẹ̀yà ara fún ẹ̀yà ara, ojú, tàbí àsọ ara.

F. **Àwọn àkànse Iṣẹ́ Ìjọba:** A óò ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ nípa àwọn iṣẹ́ ìjọba bíi àwọn iṣẹ́ ológun, ààbò orílẹ̀-èdè àti àwọn iṣẹ́ ìmọ̀ ọlọgbọ́n. A óò lò tàbí ṣé àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) sí Ẹ̀ka Ìṣẹ́ Àwọn Ológun Tẹlẹ̀ láti pinnu bóyá o yẹ fún àwọn àǹfààní kan pàtó.

G. **Àjẹsára:** A óò ṣé àfihàn ẹ̀rí àjẹsára sí ilé-ìwé níbi tí òfin ìpínlẹ̀ tàbí òfin míràn tó jọra bá béèrè rẹ̀ ṣáájú gbígba akẹ́kọ̀ọ́.

## V. Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ Nípa Àlàyé Ìlera

O ní àwọn ẹ̀tọ́ kọ̀ọ̀kan wọ̀nyí tó jẹmọ́ Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ pẹ̀lú àwọn àkọsílẹ̀ Apá Kejì (2):

A. **Ẹ̀tọ́ Láti Ṣàyẹ̀wò àti Àdàkọ:** Lábẹ́ àwọn àyàsọtọ̀ kan tí ó ní gbèdéke, o ní ẹ̀tọ́ láti ye àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ wò àti láti ṣàyẹ̀wò àti ṣe àdàkọ Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún ìgbà tí a bá ń tọ́jú àwọn àbájáde náà.

   Tí a bá kọ̀ ìbéèrè rẹ fún ìgbàláyè sí Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ, a óò jẹ́ kí o mọ̀ nípa kìkọ̀wé pẹ̀lú ìdí tí a fi kọ̀ ọ́. Fún àpẹẹrẹ, o kò ní ẹ̀tọ́ sí àwọn àkọsílẹ̀ ìtọ́jú ọpọlọ tàbí láti ṣàyẹ̀wò àlàyé tí ó wà lábẹ́ òfin tí ń dènà wíwọlé sí i. O lè ní ẹ̀tọ́ láti jẹ́ kí ìpínnu jẹ́ yìí yẹ̀wò.

   O tún ní ẹ̀tọ́ láti béèrè fún Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ lórí ẹ̀rọ ìgbàlódé ní àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí a bá ń lò àwọn àkọsílẹ̀ ìlera ẹ̀rọ ìgbàlódé.

   A óò gbà owó tó níye tó yẹ gẹ́gẹ́ bí òfin àpapọ̀ tàbí ti ìpínlẹ̀ tó yẹ.

   Fún ìrọ̀rùn rẹ, apá kan Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ yóò se wò nínú ojú-òpó aláìsàn. Àyè sí Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) ni a gba nípasẹ̀ bìbéèrè àyè.

B. **Ẹ̀tọ́ Láti Ṣe Àtúnṣe:** O ní ẹ̀tọ́ láti ṣe àtúnṣe Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún ìgbà tí a bá ń tọ́jú àwọn àbájáde náà. O gbọdọ̀ ṣe ìbéèrè rẹ fún àtúnṣe Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni

Ìdáàbòbò (PHI) rẹ ní ìkọ̀wé sí privacyofficer@trinity-health.org tàbí sí ọ̀gá ìkọ̀kọ̀ ètò wa ní 20555 Victor Parkway, Livonia, MI 48152 pẹ̀lú ìdí rẹ láti ṣe àtìléyìn fún àtúnṣe tí a béèrè fún.

Síbẹ̀síbẹ̀, a óò kọ ìbéèrè rẹ fún àtúnṣe tí:

i. A kò ṣẹ̀dá àlàyé náà

ii. Àlàyé náà ki se ara àkójọpọ̀ àkọsílẹ̀ tí a yàn

iii. Àlàyé náà kò ní wà fún ìwòye rẹ (nítorí bí ó ti rí tàbí ipò rẹ̀)

iv. Àlàyé náà jẹ́ gígún régé àti pípé

Tí ìbéèrè rẹ fún àwọn àyípadà nínú Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ bá jẹ kíkọ̀, Ọ̀gá àṣírí yóò jẹ́ kí o mọ̀ ní kìkọ̀wẹ́ ránṣẹ́ pẹ̀lú ìdí tí a fi kọ̀ ọ́. Ọ̀gá àṣírí yóò tún jẹ́ kí o mọ̀ nípa ẹ̀tọ́ rẹ láti fi gbólóhùn ìkọ̀wé sílẹ̀, tí ó tako kíkọ̀ náà. O lè béèrè pé kí a fi ìbéèrè rẹ sinu àwọn ti a fé sàtúnṣe àti kíkọ̀ náà nígbàkigbà tí a bá tún ṣe àfihàn àlàyé tí o fẹ́ yípadà lọ́wọ́lọ́wọ́. A lè ṣe àgbèjáde sí gbólóhùn àìfohùnṣọ̀kan rẹ àti pé a óò pèsè ẹ̀dà àgbèjáde náà fún ọ.

**C. Ẹ̀tọ́ Sí Ìṣirò:** O ní ẹ̀tọ́ láti gba ìṣirò àwọn àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ tí a ti ṣe, àyàfi àwọn àfihàn wọ̀nyí tó tẹ̀lé:

i. Láti mú ìtọ́jú, ìsanwó, tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera ṣẹ;

ii. Sí ọ;

iii. Sí àwọn ènìyàn tí wọ́n kópa nínú ìtọ́jú rẹ;

iv. Fún àwọn ààbò orílẹ̀-èdè tàbí ìmọ̀ èrè-ìdí; tàbí

v. Sí àwọn ilé ìtọ́jú àtúnṣe tàbí àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba tí ń ṣọ́ òfin.

O gbọ́dọ̀ ṣe ìbéèrè rẹ fún ìṣirò àwọn àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ ní ìkọ̀wé sí ọ̀gá àṣírí wa ní privacyofficer@trinity-health.org ní 20555 Victor Parkway, Livonia, MI 48152.

O gbọ́dọ̀ fi àkókò ìṣirò náà sínú, èyí tí kò lè jẹ́ ju ọdún Mẹ́fa (6) lọ. Ẹ̀ẹ̀kan nínú àkókò oṣù méjìlá (12), a óò pèsè ìṣirò àwọn àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún ọ láìsí ìdíyelé. Àwọn ìbéèrè àfikún miran fún ìṣirò nínú àkókò yẹn yóò jẹ́ kókó ìdiyele tó yẹ fún ìmúrasílẹ̀ ìṣirò náà.

**D. Ẹ̀tọ́ Láti Béèrè Fún Àwọn Ìdíwọ́:** O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè fún àwọn ìdíwọ́ lórí àwọn ìlò àti àfihàn kan pàtó ti Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ láti mú ìtọ́jú, ìsanwó tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera ṣẹ tàbí láti dènà àfihàn bẹ́ẹ̀. Síbẹ̀síbẹ̀, a óò ṣàyẹ̀wò ìbéèrè rẹ ṣùgbọ́n ọ kò nílò láti gba pẹ̀lú àwọn ìdíwọ́ tí a béèrè fún.

**E. Ẹ̀tọ́ Láti Béèrè fún ìdènà Sí Ètò Ìlera:** O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè fún ìdènà lórí àfihàn Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ sí ètò ìlera (fún ète ìsanwó tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera) ní àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí o bá san owó rẹ̀ pátápátá láti àpò rẹ fún àwọn ohun tí o gba tàbí àwọn iṣẹ́ tí a ṣe fún ọ. Àwọn ìbéèrè bẹ́ẹ̀ yóò jẹ yíyẹ́sí.

**F. Ẹ̀tọ́ Sí Ìsọ̀rọ̀ Aṣírí:** O ní ẹ̀tọ́ láti gba àwọn ìsọ̀rọ̀ aṣírí nípa Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ nípasẹ̀ àwọn ọ̀nà míràn tàbí ní àwọn ibi míràn. Fún àpẹẹrẹ, o lè béèrè pé kí a kan sí ọ nìkan ní ibi iṣẹ́ rẹ tàbí nípasẹ̀ ìméèlì. Tí o bá ti pèsè àdírẹ́ẹ̀sì ìméèlì rẹ, a lè kan sí ọ nípasẹ̀ ìméèlì náà àyàfi tí o bá béèrè fún ọ̀nà míràn láti kan sí ọ.

**G.** Ẹ̀**tọ́ Láti Gba Ẹ̀dà Ìkéde Yìí:** O ní ẹ̀tọ́ láti gba ẹ̀dà ìwé Ìkéde Àṣà Ìṣọ́ Àṣírí yìí, nígbà tí o bá béèrè fún un.

## VI. Ìrúfin Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) Tí Kò Ní Ààbò

Tí ìrúfin Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) tí kò ní ààbò tí ó kan ọ bá ṣẹlẹ̀, a nílò láti jẹ́ kí o mọ̀ nípa ìrúfin náà. Ìkéde bẹ́ẹ̀ lè jẹ pípèsè nípaṣẹ̀ alábààkẹ́gbẹ́ òwò wa ní orúkọ wa.

## VII. Pínpín àti Ìlò Àpapọ̀ Àlàyé Ìlera Rẹ

Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health àti àwọn òṣìṣẹ́ ìṣègùn ń lò Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún ìtọ́jú, ìsanwó àti/tàbí fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tí HIPAA gbà láàyè nípa àwọn aláìsàn tí a ń tọ́jú papọ̀. Nígbà tí a ń pèsè ìtọ́jú fún ọ àti nínú ìgbòkègbodò ìṣẹ́ wa láti mú ìlera àwùjọ dára sí i, a óò pín Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ pẹ̀lú àwọn àjọ míràn àti àwọn olúpèsè ìtọ́jú tí wọ́n ti gbà láti tẹ̀lé àwọn ìpèsè tí a ṣàpèjúwe nísàlẹ̀ yìí:

**A. Àwọn Òṣìṣẹ́ Ìṣègùn:** Àwọn òṣìṣẹ́ ìṣègùn àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health kópa papọ̀ nínú ètò ìtọ́jú ìlera tí ó ṣeto láti pèsè ìtọ́jú ìlera fún ọ. A ti gbà láti tẹ̀lé àwọn ìpèsè Ìkéde yìí nípa Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) tí a ṣẹ̀dá tàbí tí a gba gẹ́gẹ́ bí ara ìpèsè ìtọ́jú ìlera fún ọ. A óò gbà làti lò Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) láti mú ìṣẹ́ àánú wa ṣẹ, pẹ̀lú àyẹ̀wò àti dídárasi ìtọ́jú.

**B. Ọmọ Ẹgbẹ́ nínú Trinity Health:** Àwa àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ míràn ti Trinity Health kópa pọ̀ nínú ètò ìtọ́jú ìlera tí ó ṣeto fún àyẹ̀wò ìlò, ìwòye ìdánra wo, àti àwọn iṣẹ́ tí ó jọmọ́ wọn. Gẹ́gẹ́ bí ara Trinity Health, ètò ìtọ́jú ìlera Kátólíìkì tí ó jẹ́ ti orílẹ̀-èdè, tí ó fi mọ àwọn ilé ìwòsàn míràn, àwọn ilé ìtọ́jú àgbàlagbà, àti àwọn olúpèsè ìtọ́jú ìlera pín Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ fún àyẹ̀wò ìlò, ìwòye àyẹ̀wò, àti àwọn iṣẹ́ tí ó jọmọ́ wọn ti Trinity Health, ilé-iṣẹ́ ìyá, àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ rẹ̀. Gbogbo àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health ti gbà láti tẹ̀lé àwọn ìpèsè Ìkéde yìí nípa Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) tí a ṣẹ̀dá tàbí tí a gba gẹ́gẹ́ bí ara àwọn iṣẹ́ àyẹ̀wò ìlò àti ìwòye àyẹ̀wò.

Jọwọ́ lọ sí àwọn ojú-òpó ẹ̀rọ AyélujáraTrinity Health fún àtòjọ àwọn àjọ ọmọ ẹgbẹ́ ní http://www.trinity-health.org/. Tàbí, ní ìyàtọ̀, o lè pe Ọ̀ga àṣírí wa láti béèrè fún ohun kannáà ní 833-718-1043, tàbí o lè fi ìméèlì ránṣẹ́ sí wa ní privacyofficer@trinity-health.org.

**C. Àwọn Alábààkẹ́gbẹ́ Òwò:** yi óò pín Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ pẹ̀lú àwọn alábààkẹ́gbẹ́ òwò àti àwọn onise kékèké wọn tí a ti ṣe àdéhùn láti ṣe àwọn iṣẹ́ òwò ní orúkọ wa, pẹ̀lú Trinity Health, tí ó ń ṣe àwọn iṣẹ́ òwò kan fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ wa.

**D. Àwọn Olúpèsè Ìtọ́jú Ìlera Rẹ àti Àwọn Alájọṣepọ̀ Ìtọ́jú:** O gba ìtọ́jú tí a pèsè nínú àyíká ìtọ́jú tí ó ṣọ̀kan, níbi tí àwọn aláìsàn ti ń ríran nípaṣẹ̀ àwọn olúpèsè tí ó yatọ̀ àti ní àwọn àyíká ìtọ́jú tí ó yatọ̀ gẹ́gẹ́ bí ara ìtẹ̀síwájú ìtọ́jú àti ìpèsè ìtọ́jú tí ó ṣọ̀kan. A pín Àlàyé Ìlera tí ó ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ pẹ̀lú àwọn olúpèsè ìtọ́jú ìlera míràn àti àwọn alájọṣepọ̀ ìtọ́jú tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ pọ̀ láti pèsè ìtọ́jú, gba owó ìsanwó, àti ṣe àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera. Àlàyé Ìlera tí ó ni

Ìdáàbòbò (PHI) rẹ ni a pín ní ọ̀nà ẹ̀rọ onírúurú ọ̀nà pẹ̀lú àwọn olúpèsè ìtọ́jú tí wọ́n kópa nínú ìpèsè ìtọ́jú àti ìṣọ̀kan ìtọ́jú. Àlàyé Ìlera tí ó ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ lè jẹ pínpín nípasẹ̀ ìsopọ̀ tààrà sí ètò àkọsílẹ̀ ìlera àlàkalẹ̀ ti àwọn olúpèsè ìtọ́jú míràn. Àlàyé Ìlera tí ó ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ lè jẹ pínpín nínú pàṣípààrọ̀ àlàyé ìlera tàbí nípasẹ̀ ìmọ̀ ẹ̀rọ tí ó jẹ́ kí àwọn olúpèsè ìtọ́jú àti àwọn alájọṣepọ̀ ìtọ́jú tó wà ní ìsàlẹ̀ ọ̀nà lè gba àlàyé rẹ. Àlàyé Ìlera tí ó ni Ìdáàbòbò (PHI) rẹ lè jẹ pínpín nípasẹ̀ gbígbé àlàyé tí ó ní ààbò sí àwọn apótí ìgbà àwọn olúpèsè ìtọ́jú míràn.

**VIII. Àwọn Àyípadà sí Ìkéde yìí:** a óò tẹ̀lé àwọn ìpèsè Ìkéde tí ó wà ní ìṣísẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́. A ni ẹ̀tọ́ láti ṣe àwọn àyípadà pàtàkì sí àwọn ìpèsè Ìkéde rẹ̀ àti láti mú àwọn ìpèsè Ìkéde tuntun ní ìṣiṣẹ́ fún gbogbo Àlàyé Ìlera Tí Ó Ni Ìdáàbòbò (PHI) tí a ń ṣọ́. A óò pín / pèsè Ìkéde tí a ti ṣàtúnṣe fún ọ ní ìbẹ̀wò rẹ àkọ́kọ́ lẹ́yìn tí a ti ṣàtúnṣe Ìkéde náà - áìmọ níbi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí a bá ti ṣe àyípadà pàtàkì nínú Ìkéde náà. O tún lè bèèrè fún ẹ̀dà tuntun ti Ìkéde nígbàkigbà. Àwọn ẹ̀dà tí ó jẹ́ tuntun ni a ti filelẹ̀ sórí àwọn ojú-òpó ẹ̀rọ ayélujára ti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health.

**Fi ẹ̀sùn kan:** tí o bá gbàgbọ́ pé àwọn ẹ̀tọ́ àṣírí rẹ ti jẹ rírú, o lè fi ẹ̀sùn kàn pẹ̀lú Ọ̀gá àṣírí wa tàbí pẹ̀lú Akọ̀wé Ìjọba Ẹ̀ka Ìlera àti Iṣẹ́ Ènìyàn. Pẹ̀lú èyí, àwọn ẹ̀sùn lè tún jẹ fífi ránṣẹ́ sí wa ní privacyofficer@trinity-health.org, tàbí nípa pípe 833-718-1043, tàbí sí ọ̀gá àṣírí ètò wa ní 20555 Victor Parkway, Livonia, MI 48152.

***IX. A kò ní gbẹ̀san sí ọ fún ẹ̀sùn tí o bá fi kàn.***

Òsìsé àṣírí – Àwọn Ìbéèrè / Àwọn èrò / Àlàyé Àfikún: Tí o bá ní àwọn ìbéèrè, àwọn èrò, tàbí o fẹ́ àlàyé síi nípa àwọn ọ̀rọ̀ tó wà nínú Ìkéde Àṣà Ìṣọ́ Àṣírí yìí, jọwọ́ kan sí ọ̀gá àṣírí wa ní 833-718-1043, tàbí o lè fi ìméèlì ránṣẹ́ sí privacyofficer@trinity-health.org.